## ỌRỌ LORI IJO KU SI MI LAYA

Lati Ọwọ Ọmọ'ba Olu. Adegbayibi P. 4 Ibokun)

Olotu jọwọ ma sai gba mi laye, ninu iwe irohin rẹ ti ọsẹ yi, lati sọrọ si awọn ọdọmọkunrin ati Ọdọmọbirin ti oju ko ti larin Igboro ti wọn ro pe on to dara ni iru ijo kan ti o buru ti wọn jo ni akoko Ajinde; ti wọn npe ni ku si mi laya. Awọn ti ijo ko dun mọ ninu, ti kọ iwe nipa rẹ lati ilu pataki gẹgẹbi Eko, Ibadan, ati Abẹokuta, sinu iwe irohin Daily Times, Service ati bẹbẹ, pe iru ijo yi ko dara lati ri pe Ọmọbirin ati Ọmọkunrin, ti o ni Iya ati Baba ti o le ba wọn wi lati ma jo iru ijo Pansaga yi.

Ti a ba ni hi a ma tumọ ijo yi:- ku si mi la ya, o pọ pupọ o si buru.

IJO NA KỌ ENIA NI PANSAGA:-

Ni gbati obirin njo larin igboro, ti nfi lọ si ẹhin ti ọkunrin ki ẹsẹ kan bọ labẹ ti o da aya de ni arin ilu lalẹ pe aja ni wọn. Ti nwọn nkọ orin ainitiju pe, Ẹ ti ma tu seti rẹ ta; Ẹ ti ma tu Beed rẹ ta. Kini itumọ orin korin, ti o ba jẹ pe wọn ni ronu ati alabawi, ti o jẹ pe ko si ọkan ninu wọn ti o le ronu ti wọn sọ ara wọn ara wọn di Aja ti wọn sọ ara wọn di alainironu Ẹgbẹ buburu ni o ma mba iwa rere jẹ: Nitorina o yẹ ki awọn Ọdọmọbirin ati Ọdọkunrin wa, mọ pe ijo yi ko tọ si wọn. Ko yẹ ki wọn kọ asa buburu nipa ijo ki'jo

Awọn enia pataki ti ko jade lati ọpọlọpọ ilu fi wa pe ki wọn ma ba ilu wọn jẹ fun wọn; nipa iru ijo buburu yi:- Ọpọlọpọ obi ti ẹnu rẹ ka ọmọ rẹ ni o ti nmu ọmọ wọn kuro ninu Ẹgbẹ ku si mi laya. Ẹ jọwọ ẹ jẹ ki akọ asa to dara. Gbogbo bi ati nse ni enia awo wa Ninu awọn ọdọmọkunrin ti o ba ni Iyawo ninu awọn onijo Ajinde ti o si ri Iyawo rẹ ti okunrin lẹmọ tipẹ tipẹ inu ẹni bẹ ko le dun ẹ jọwọ ẹ jẹki a se Ikilọ fun awọn Ọdọmọkunrin ati Ọdọmọbirin wa, pe ki nwọn ye jo ijokijo ati orin korin

Mo fẹ ki ẹ mọ pe Ijesa jẹ ọkan ninu awọn ilu pataki ti o wa ni Iwọ Orun o si jẹ Olu ilu fun ilẹ Ijẹsha. Ko yẹ ki awọn agbegbe ti oyi wa ka ki o ma fi ẹsun ti ko dara yi kọ wa lọsẹ, tori o yẹ ki nwọn ma wo ... kan ti a ba nse ki awọn na ma se ko yẹ ki afi apẹrẹ buburu silẹ fun awọn ọmọ ati aburo wa tio mbọ lẹhin gẹgẹbi awọn ọmọ Ilewe. ọpọlọpọ ni awọn ti afi owo ko ninu awọn ti o njo ijo ki jo yi ti wọn ko lo ọpọlọ Ọgbọn ẹkọ wọn kini a tọ wọn fun? Ẹ jọwọ ẹyin onkawe, wo awọn Ọmọbi-

(Bẹrẹ ni oju iwe 6)



ALHAJI A R A SMITH

Ọgbẹni Akibdele Ojo nbẹ awọn to fẹran ire ati alafia Ilẹ Ijẹsa bi Alhaji wa yi pe ki wọn kuro ninu Ẹgbẹ Ọiọpẹ nitoripe iwa ti wọn dara ju ti Ẹgbẹ na lo.

## IFILO PATAKI

Awọn Alakoso ile iṣe Ijesha Press Ltd. ni ki aṣe ifilọ yi fun gbogbo awọn ẹniti wọn da owo sinu iṣẹ yi yala ni ilu Ilesha tabi Idale pe afẹ ki onikaluku fi akọtan orukọ rẹ ranṣẹ si Office Ijesha Press Ltd ni B.110 Okesha tabi P.O. Box 23 Ilesha.

Fun apẹrẹ ẹniti oba njẹ J. O. Aina afẹ ki o sọ orukọ ti J. O. duro fun, ki aba le fi akọtan orukọ yi sinu iwe ti ao fi ranṣẹ si onikaluku laipẹ yi.

Alabojuto



ỌGBẸNI E. A. ỌKẸ

On ni Akowe awọn Ẹgbẹ Alaṣọ ati alate ni Ilesa. Iya Agba Rebeka Opeluo jẹ ọkan pataki ninu wọn ni agba aiye rẹ. Iya Agba na ku laipẹ yi. Ọgbẹni wa yi pẹlu awọn to lọ si ibi isinku rẹ.


# WANTED URGENTLY

**Four Journey-men and Four Apprentices.**

Apply in person to the Foreman:

Ijesha Press, Limited:

P O Box 23, ILESHA.


## AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

Afẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si 'gbogbo ipade dede.



ỌGBẸNI J O OGUNSEITAN

Ọgbẹni S Akindele Ojo nbẹ awọn enia daradara dię bi Alagba yi to wa ninu Ẹgbẹ A G pe ki wọn kuro ninu Ẹgbẹ na ki awọn na le wnlo fun Ilẹ Ijẹṣa.


# E FI IROHIN IPADE IGBIMO YIN

SỌWỌ FUN TITẸ JADE NINU

# Irawo Obokun


## ISAIAH AJAYI JẸ OYE JAGIỌ

(Lati Ọwọ Jonah Ade. Alewowo P. o. Box 21 Ẹsa Odo)

A'i Isaiah Ajayi jẹ Oye Bab rẹ ni ọjọ kẹrinlelegun oṣu tini ọdun 1955 nipa aṣẹ Ioye Ẹjẹmọ ti o jẹ Lẹja tiẸsa Udo pẹlu awọn Ijoye'ẹ Eyiti gbogbo Ọdọ pejọ adugbo wọn ni Oke Aba ibiti ati fi jẹ Oloye yi han aọn ọmọ ilu ati Agba ilu ka fi jẹ oye na gẹgẹbi aṣa Ilẹ wa. Lẹhin eyi ni Ọba w Oloye Ariyo wọn ye Ẹjẹn ojẹ ti Ẹsa-Odo sure fu Asi tẹlẹ Oloye yi losi ilẹ pẹlu oni ruru ilu ati Ijọ, si pe gbogbo ọrẹ ati ojulumọ oloye yi sibi ase nla ati pese fun wọn, bẹni nw jẹ ti nwọn si mu pẹlu

Oloye gio ṣe ijade Oye ni ọjọ keje a fi jẹ eyi ti anpe ni Ije Oyin ọjọ kọkanlelogun oṣu ini ọdun yi

Awọn ẹ oselu eyiti Oloye yi jẹ ga wọn ba se idupẹ oye ni ile isin ti Ijọ Afirika ọjọ kẹtala oṣu k eji ọdun

Awọn ti si ba lọ sibi idupẹ na nwọnyi:- Oloye olumọkọ, un, Loyin, Lẹmọ, Ọdọ'in, Ọbanla, Ajagutẹ Olaiya ati awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pẹlu Jona Ade: Alewowo, Isaac Adogun, E O Odurinde, S. Ẹsọ, Jacob Aje Sam. Efọnjoko, Sam. Ademokoya, G. Ojo Oyedele Daniel Ajakaiye, G Ọlayinka Salami Arunko ati arabirin Alice Ona, Alice Ọmọlẹyẹ

## OKE AIYEDUN EKITI

## OLOYE SAMUEL FALADE ELEBUTE PARADA

Ni ọjọ keje oṣu April 1955 ni dede ago mejila oru ni Oloye wa yi parada ti o si lẹ jẹ ipe Ọlọrun abi Ọgbẹni yi ni nkan bi ọdun 1866 ni Ilu rẹ Aiyedun Ekiti.

Ọgbẹni Oloye Ogundilẹ ati Yemisi jẹ akinkanju enia pupọ Oloyẹ na jẹ ọkan ninu awọn olumọna isin Igbagbọ Wesileyan ti an pe ni (Methodist) Ijọ eleto, nisisiyi ni ilu Aiyedun ati agbegbe rẹ

O fi awọn ọmọ pupọ silẹ lọkunrin ati lobirin, orukọ awọn ti ko le gba iwe yi, ninu awọn ọmọ rẹ ni Ọgbẹni Z. O. Elebute Ileṣa ati ọgbẹni wa Dr. M. K. Ejirẹ (HEALTH AND WELFARE CENTRE) Ijẹbu Ode.

## SI ADABANLA OJU ỌJA MORIRO AIYEDUN EKITI

(Lati Ọwọ Aiyekotọ Alawiye Koṣẹṣẹ St. Aiyekọlẹgbọn)

Ọrẹ mi ọwọn, Ẹ ku ọginitin yi ṣe alafia ni gbogbo awọn ara ile wa? Owiwi nkọ? mọ gbọ wipe Ọgbẹni Owiwi ti nran awọn ọmọ rẹ lọ si ile iwe Ọgbẹni Aṣa ori Iroko Ṣigidi ajuna ni Ikọle Ekiti, ṣe ko ni pa lọmọ jẹ tan bayi? anu Owiwi ori igi ẹṣiẹ ni odo ọrọ Ekiti ma ṣe mi pupọ o. Ọrọ pataki ti mo fi kọwẹyi si yin ni wipe mo gbọ wipe iwọ ati Aṣa ori iroko ṣagidi ajuna Ikọle Ekiti ti tẹ ọrẹ pọ nisisiyi ati wipe wọn fẹ pari ija ti o wa larin yin ni lọwọ lọwọ yi, Ah! Ẹru aṣa ma gba mi o, maṣe gbọyẹgẹ aṣa rara o, emi ko fẹ ki o ba ṣe ọrẹ pọ o, nitori ko iti ge ekekanna ọwọ rẹ ṣobọlọ ijọṣ o yio ma pa ọ lọmọjẹ sibẹ, mo wi fun ọ o, nitori iwọ ti jẹ oniwatutu ẹiyẹ pupọ inu kan ni iwo si nlọ larin awọn ẹiyẹ o

Ṣugbọn aṣa jẹ aladakandẹke ẹiyẹ pupọ, ti o ba gbe ọdiẹ orukan tan ti o ba bẹẹ ko kọ lati lọ bẹ awọn Ọba eyẹ Okin ati ayaba Ologoṣẹ wa bẹ orukan, nitori on le lọ gbadiẹ lọ bẹ awọn ọlọla ẹiyẹ ọkin ati alogoṣẹ wa bẹ orukan nitori on le gbadiẹ lọ bẹ ọawọn ọlọla ẹiyẹ Ọkin ati ologoṣẹ wọnyi fun nidi Ọkẹ ni o maṣe ba jẹ, maṣe ba mu o, nitori ti o ba ino pada dọrọ gẹdẹgbẹ emi ko ni da si o, ranti awọn ọmọ ẹiyẹ ọdiẹ rẹ ti o fi ọgbọn ẹtan ko lọ mijọṣi; ti o sọ wipe on yio ma pa kọlọkọlọ fun wọn jẹ ni on ṣe fẹ ma ba wọn gbe asẹbinwa on asẹhinbọ, tani ko mọ wipe a ko le pa kọlọkọlọ fun ọmọ adiẹ kankan pajẹ, laiye yi ayafi ti a ba pa ọdiẹ fun kọlọkọlọ, ranti awọn ọrọ mi wọnyi ki o fi sọgbọn o; afibi ṣọlọre ni aṣa o, o ti bẹrẹ sifibi ṣu emi o, emi ti mọ ọtitọ lojumọ aṣa sọ mi di alagidi ati ọlọkan lile, ṣugbọn o nipa temi o, emi ko le fi oriji rara nitoripe ẹlẹṣẹ ki yio lọ lai jiya, iyan ọdun mẹta njo ni lọwọ. Tete fesi iwe yi nitori kole ṣeṣẹ bẹ o nitori ko sọbọ ni dere mọ o, nitorina ẹ ma fi kuku ba ẹjọ yin lọ lọdọ adajọ Ọgbẹni Kanrakanna adajọ awọn ẹiyẹ gbogbo o.

Nipa temi "Salamọleku" ni temi o, ọrọ kan ku sinu imale o ma ba mi ki awọn aya rẹ ati ọmọ rẹ o, maṣe jẹki aṣa wa ma agbado loko rẹ mọ bọ awọn ọdiẹ rẹ ti a wa fi ọgbọn ẹtan ma lọdọ rẹ, jẹki o ma pa kọlọkọlọ ti o ṣe ileri fun wọn jẹ a ki kuro nilu ka bere ẹkọ ibẹ o.

## OKE AIYEDUN EKITI IYA AFIN LEA ṢE AJỌYỌ EWU ṢANGO

Ni ọjọ keje ẹṣa yi moju ọjẹ kejọ ti mọ ọjọ Isinmi ni Arabirin wa Lea Ọladimeji ni ile rẹ ni adugbo Orisunbare ṣe ajọyọ ati ariya nipa ewu ṣango ti o bale ni ile rẹ, dię lọ ku ki arabirin yi farapa nipa idagiri yi ṣugbọn Olorun gbe leke ọta

O ṣe gudugudu meje, iyọ ati ya yi, ọrọsisi onjẹ ati mimu to kari ilu na ọpọlọpọ enia ja kankan ni arabirin ọmọ'ba yi gba lalejo bi awọnyi:- J. O. Fulani Dr M. K. Ejirẹ, J. O. Ọlaniyan, J. A. Filani, Omidan Mary Alao, Master David Fọlọrunṣọ Mojọla ati awọn bẹbẹ ti a ko le kọ sinu iwe yi, Ọgbẹni Babalọla ati awọn ẹlẹgbẹ oni kakọmọ rẹ ni o ṣere moju a ki Iya afin ku ori rẹ o Lea wa Ọgbẹgun awẹlẹwa. Bi o mọ nṣere, salaye, ti ki ja ti oba ku ki Oluwa ma yọ ọọ Aṣẹ.



ỌGBẸNI D. D. LAYIKA

On ni Oluko Agba fun Ile Iwe Ifẹ Oluwa Oke Ẹsọ, on na si jẹ ọkan ninu awọn ogunagbongbo ninu Ẹgbẹ Afẹnifẹre o wa pẹlu awọn enia pa aki to wa sibi ipade ti awọn Obirin Afẹnifẹre ṣe laipẹ yi.

## IPADE LARIN KANSELỌ PẸLU ASANWO ORI

(Lati ọwọ Kanselọ J B Awẹ)

NI alẹ ọjọ satide eyiti nse ikọwọ ọgbọnjọ osu kẹin odun 1955 kan-elọ J B Awẹ ẹniti o nse oju awọn asanwo ori ti w-ard A 3 odo-Eshẹ pe gbogbo awọn asanwori ti o wa ninu ward rẹ jọ lati gba wọn niyanju ati lati se alaye nipa iru Ijọba ti o wa lode oni abẹrẹ ipade na ni waju ile oloye Arapatẹ ni dede nkan bi agogo marun abọ irọlẹ pẹlu adura.

Kanselọ J.B Awe ṣe alaye pe lati igbati awọn Ọba ti nikan nipasẹ lori wa titi ofi di asiko ti awọn ọmọ ilu ni asoju kan si arin awọn ijoye lati ma ba wọn domoran, sugbọn lode oni bayi Ijọba ti yatọ si gbogbo eleyini awọn ọmọ ilu lo ni asoju ninu Ijọba ti ode oni kanselọ mẹta ijoye kan nitori eyi ọwọ ọmọ ilu ni eto ati Ijọba ilu wa. Ki awọn agbagba ati ijoye tagiri ki won ba aiye yi si ibi tio ba ti nyi si lojumo nitori pe aiye ko duro loju kan soso rara o awa ko dẹ waiye ati jẹ agba nija.

Lehin eleyi Kanselọ J B Awẹ wa fi ye awọn enia na gbangba pe ani orisirisi isẹ lati se larin ilu Ijẹbu-Jesha awọn isẹ bi ọna ati wa ilera ọna iru ilu wa, oja wa lati tunse, awa tikolese eleyi laisi ifọwọ sowọpọ awọn ọmọde ilu, Agba ilu ijoye ilu ati awọn obiri ilu siwaju si Ọgbẹni kanselọ J B Awẹ yi tunbọ laye ni siwaju si wipe awọn kan wa ti o jẹpe oyẹ ki wọn ma san owo onipo ti wọn nsan owo mẹkunu bẹni awọn kan tun wa ti o yẹ ki wọn ma san owo mẹ kunu ti wọn nsan owo oni po gbogbo iru eyi ko dara Ijọba ti Ẹgbẹ Alakukọ (N C N C) se tan lati wadi gbogbo eleyi k nikini ki wọn si se a.unse ti oni lari lori wọn. Nigbati ao ba seto si san owo ori, papa awọn ti ki fẹ san owo ori, gbogbo wọn lao fa jade lati dawo ori ki a lẹ ri owo lo fun ilọsiwaju ilẹ wa.

Kanselọ Awẹ tun se alaye lori bi wọn ti se yan alaga igbimọ wa ti ko fi tẹ Ọba wa lọwọ eleyi kise inunibni tabi ikorira orirere ẹni ti a fi se alaga lo gbede aye yẹn Eyini ni kanselọ B O Orioke ẹniti o tun nse igbakeji alaga ti igbimọ gbogbo Ilesha (Divisional Council)

Otun se alaye lori iwa ti baba wa hu nigbati alaga igbimọ wa sope ki Ọba wa dide tio ba fẹ sọrọ ninu ipa de igbimọ Ọba si sọrọ abuku si alaga wa larin ipade ele-yi tabuku ẹni lọpọ lọpọ bi

Bere loju iwe 6



OLOYE AROJOJOYE KEJI OGBONI IJẸBU-JEṢA

On jẹ ọkan pataki ninu awọn Ijoye ti Ile Ijesa, on na wo pelu ogunlọgọ awọn Oṣelu ilu rẹ nibiti Kanselọ J B Awẹ tise alaye lori eto igbekalẹ Ijọba titun ninu ipade ti aṣe ni adugbo Odo Ẹsẹ Ijẹbu-Jeṣa laipẹ yi.



ỌGBẸNI J. O. GILBERT

On jẹ Ọga Wọnlewọnlẹ (Surveyor) ti Ilẹ Ijẹṣa, on na wa pẹlu ogunlọgọ awọn enia pataki ti o wa si Banusọ lati ṣe aseyẹ fun awọn Ẹgbẹ Obirin Afẹnifẹre ti o ṣe ipade lọjọ isimi tiṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi.

## ỌRỌ LORI POST OFFICE ATI DISPENSARY

(Lati ọwọ Joel Awopẹtu Ado Odo)

Saju ọrọ mi mo juba Edumare ti nse alakoso enia ati Ẹda ohun gbogbo ti nra-ko. lẹhin na mo wa juba Olotu Irawọ Obokun ti nse Olotu iwe yi? Ẹko ni si isẹ yin se lagbara Edumare, aja-lule awolulẹ kipa ologbo on ekute ile yi, Ẹ ko marin lọjọ ti ebi npa ọna Amin.

Bakanna ni mo ki awọn oka'we Irawọ Obokun ni ile ati ni idalẹ lẹkan si mo ki Ọba Ajimọkọ keji, Ijoye ati awọn Kanselọ Ilẹ Ijesa laiku ẹnikan, pataki ohun ti mo fi kọ iwe yi sinu Irawọ Obokun lọsẹ yi ni ọrọ kan ti mo kọ jade ninu Irawọ Obo-kun ti oṣu keji ọjọ kẹrindin-logun 1953 oju iwe keje, eyi ti nse ọdun meji ati oṣu mẹrin bayi ọrọ na ni Post Office Iwara ati (N A ) Dis-pensary, wọn bẹrẹ si awọn isẹ ti mo darukọ wọnyi, sugbọn eyi ti o yami lẹnu ni-pe lati bi ọdun kan abọ ni wọn ti bẹrẹ isẹ yi wọn ko pari rẹ rara: eyi ti wọn pa-ri wọn ko sisẹ ninu rẹ Iwa-ura si Ilesa jẹ Ibusọ meje 7 Mls. Awọn ilu agbebe bi Iyinta Iwikun, Oko'gbo morope Miles Iyinta na Ilesa to ibusọ mẹfa (6) M. Igbamsran ki wọn ko iwe wọn ran ọmọde ki ọmọde na sọ iwe na nu, tabi ki sọpe on gbagbe osoro ki enia to ri iwe kan lọsi Ilesa laijẹpe omura ile lẹ idi ni yẹ ti nko fi ri dede, bẹni emi papa o-rope o rọrun fun ẹni:ni lati lọ si ibusọ meje ibi ibusọ mẹfa (6 Mls.) fun iwe ransẹ sa

Mo bẹ gbogbo awọn Kan-selọ Ijẹsa papa ỌlọlaFa-dahunsi ati awọn Ẹg rẹ ati bawa risi ipari wọn isẹ na laipẹ yi

A fi awọn ọrọ na olo-ye Awara ti ilu Iwaraọwọ; ọrọ na di ọwọ awọ Kan-sẹlọ ọna Iwara laida nikan i lati bojuto awọn na, awọn agba ma npa ẹ kan bayi pe, agbatan igbọlẹ ti a ba dasọ fun ọmọ pa laro, mo fi owe juba awọn agba Olotu dupẹ fun aye ti ẹ gba mi, Oluwa alafia ki o ma fi ia ba ba gbogbo wa gbe isisin-yi lọ ati titi lailai nin

## REBECA ỌPẸTUO SUN NINU OLUWA
(Lati Ọwọ Joel Awopetu Ado Odo)

Iyawo, Madam Rebecca Opetuo sun ninu Oluwa ni ọjọ 6: 5: 55, ni dede agogo mẹta ati abọ (3. 30:) ọsan.

Ologbe yi jẹ ọmọ ọdun marunle-ladọta (55 years), A si gbe ologbe, yi ni iyawo fun Ọgbẹni Daniel. Ale. Olọwe ni adugbo Igbogi ni Ilesa ni nkan bi ọdun marundin-logoji sẹhin (35 years)

Nigbati Ọkọ rẹ nṣe owo ni idalẹ; o jẹ olurannlọwọ kan pataki fun u. O pada de si Ilesani nkan bi ọdun mẹta sẹhin. Lẹhin igbati o ti de si Ilesa, lo ti bẹrẹ si ṣe owo aṣọ tita ati owo apo. Nipa si ṣe bayi, o wọ Ẹgbẹ Alẹṣọ Ilesa ni nkan bi ọdun kan sẹhin. O si jẹ ọkan pataki ninu Ẹgbẹ na ki o to di ologbe.

Ninu Ijọ Apostolic (Aladura) ti Igbogi, o jẹ koko kan pataki Awọn to wa si ibi isinku rẹ fẹrẹ to Ẹgbẹrun meji enia. Nitori ọpọlọpọ awọn enia lo ti orişirişi ilu wa, bi Ikirun, Oşogbo, Ibadan ati awọn ilu miran ti a ko le ma ka lẹsẹsẹ.

Lẹhin isinku rẹ, awọn ọmọ-loku ati awọn ebi rẹ ṣe kisa. Nwọn fi ijo pẹtẹ asemẹju ni nwọn ṣe ire. Orişirişi ilu lo wa nibi isire yi

Ni ọjọ Satide ati ọjọ ọsẹ (7-5-55 ati 8-5-55). awọn ọmọ loku fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn to wa ba nwọn ṣe eyẹ lọrun.

Ni ọjọ ọsẹ ti nṣe 8-5-55, lẹhin isin arọ, gbogbo Ijọ lokunrin lobirin pẹlu awọn Oyinbo wọn meji wa si ile Ọkọ ologbe na lati gbadura fun ati fun gbogbo awọn ebi ologbe na.

Lẹhin igbati nwọn ti gbadura tan, ti awọn Oyinbo si ti lọ n' awọn ọmọ loku ati awọn ebi rẹ bẹrẹ si ko jijẹ ati mimu silẹ.

A jẹ sẹku ni gbogbo awọn enia to wa sibẹ jẹ ti nwọn si mu pẹlu

A ṣe ijade ologbe yi ni Ijọ Aladura ti Igbogi ni ọjọ ọsẹ ti nṣe ọjọ 15-5-55.

Lẹhin isin, gbogbo ijọ lokunrin lobirin ati ọpọlọpọ awọn miran ti ki nṣe ijọ, şugbọn to wa ba awọn ọmọ loku ṣe ijade lo ba wọn wale.

Awọnt ọmọloku si tẹ gbogbo awọn enia nwọnyi lọrun nipa jijẹ ati mimu.

Irohin ko to afojuba. Ọmọ ko ayọle, eni ọmọ sin lo bimọ.

Awọn pataki diẹ to wa s' ibi isiku na ni Ọgbẹni E. A. Ọke, E A. Joshua, Fagbemi, Eman Ọgini George Olọwẹ, Abe, Chief Lọjabala, Babalọla Areke, Josiah Ojofeyitimi ati awọn ọpọlọpọ miran



ỌGBẸNI S. B ORIOWO

On jẹ Onisowo kan pataki ninu awọn ọmọ Ijẹşa Obokun o Omi Adio, on papa wa ninu awọn tio nwa ire ilu Ileşa ni Idalẹ ti wa nitoripe ọpọlọpọ iwe isiri lanri lati ọdọ rẹ eyiti yio jẹ fun igbega ilu:

## FUN GBOGBO OMỌ ẸGBẸ ACTION GROUP ỌPẸ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Action Group mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede. AKỌWE



AṢABIRIN B T OGUNSEITAN

On jẹ ẹnikan pataki ninu awọn obirin Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Ilẹ Ijẹşa o si wa pẹlu ogunlọgọ awọn Obirin ẹlẹgbẹ rẹ ti o ṣe ipade pataki ni ogba Ilanuşọ ni ọjọ kẹjọ 8 5 55 ọjọ yi on na si ba wọn sọrọ isiri.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | OJU EWE KINI | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inşi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |
| | | OJU EWE KEJI | |
| Igba | 1—12 | 5s | fun inşi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |
| | | OJU EWE KẸTA | |
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. " " " | |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |
| | | OJU EWE KEJỌ | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inşi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

## OGUNIKẸ OTIMI JẸ ỌTUN ẸGBẸ BASIRI

Lati ojọ s tide tise ọjọ keje osu yi, ni arabinrin Ogunikẹ tise iyawo Otimi ti adugbo Okesha ti nse imurasilẹ fun ti inawo oye ti awọn ẹgbẹ rẹ fijẹ larin ẹgbẹ Basiri. On pelu bale ati awon iyawo ati ẹbi wọn si ti pese orisirisi onjẹ silẹ.

Nigbati odi owurọ ọjọ isimi tise ọjọ kejọ ni ẹsẹ awọn ẹgbẹ yi ti pe silẹ Ogunikẹ lati wa ba se aseyẹ na, bi wọn si ti nwọle ni aba mu onikaluku wọn lọ si ibiti ati pese aye alẹ fun wọn, bakanna ni asi ngbe onjẹ ati mimu siwaju wọn. Onikaluku awọn ọmọ ẹgbẹ ti owa sibẹ lo si jẹ onjẹ ajẹti.

Bi aseyẹ yi ti nlọ lowọ ni awọn ẹgbẹ Iranlọwo gbajumọ Club ba de lati wa se aseyẹ fun iyawo ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ won bi awọn ẹgbẹ yi si ti de ni ọgbeni Otimi tise ọkan pataki ninu ẹgbẹ na ba fi ile pọti osi fena roka, ajẹti ni onikaluku wọn jẹ onjẹ ti awa silẹ Bi awọn ẹgbẹ okuurin ti jẹhun tan ni aba gbe ogidi ẹmun ile Alaji kalẹ niwaju wọn gbogbo awọn lo si mu ẹmu yi lo gbadu[n] rẹ toripe bi ọti oyinbo ni ẹmu Alaji na ri.

Nigbati odi agogo mefa irọlẹ ni onilu adamọ Sọke wa sibẹ wọn si fi ilu ati orin da bira sibẹ awọn ẹgbẹ obirin Basiri yi ati Iranlọwo gbajumọ Club bẹrẹ si fi ijo bẹ arabirin Kinla tise iyawo ọgbẹni Oye Aluko ti adugbo ọmọfẹ ni iyalode ẹgbẹ yi ogunlọgọ awọn enia pataki pataki lokunrin ati lo birin lo pese sibẹ asi pari aseyẹ yi ni agogo mẹsan irọlẹ pẹlu jijẹ ati mimu.

Akọlẹ olotu aki ọgbẹni Otimi ẹkun, Ogunikẹ, ati awọn idilẹ wọn pe wọn ku inawo, Ọlọrun yio jẹki oye mọ lori, asi tun ki arabirin Kinla Iyalọde ẹgbẹ Basiri awọn oloye ẹgbẹ ati gbogbo ọmọ ẹgbẹ patapata pe wọn ku aseyẹ, ki Ọlọrun fi ẹsẹ ẹgbẹ mulẹ ki wọn mase ri iku ojiji larin wọn obun ayọ beyi yio kari gbogbo ẹgbẹ o asẹ.

---

# WANTED

## Secretary | Treasurer

Minimum qualifidation : CLASS IV, Salary, hours of work etc. fixed on interview. Two bondsmen a necessity.

Apply Chairman, Mu:oko Local Council, via Z 102 Ijofi Street, Ilesha. Latest 30 : 5 : 55.

ATAIYERỌ, THE ARARỌMI
Chairman

---



ỌMỌ'BA ADELUPỌ OGUNMOKUN

On jẹ ọkan ninu awọn Ọmọ'ba Ilesa, o si jẹ enikan pataki ninu awọn Ijesa Obokun ti o wa ni Eko, igba pupọ lo ngbinyanju ati wa ire ilu na, irufẹ iwa yi lo mu ki ọpọ enia fẹran rẹ



OMỌ'BA E. ADE GBADEBỌ

On jẹ enikan pataki ninu awọn ọmọ Ijesa ti o wa ni ilu Abẹokuta, igbagbogbo ni o si ma nkọwe sinu Irawọ Obokun osi nira awọn enia ieti pe ki onikaluku mura lati wa ire ilu rẹ, oo na jẹ ọkan ninu awọn ti on wa ire ati igbega ilu rẹ pelu

---

# WANTED

## A Secretary | Treasurer

FOR ILUPEJU LOCAL COUNCIL, ATORIN.

**QUALIFICATION** :— Govt. Class IV or Equivalent.

Preference will be given to Applicants with good knowledge of Typing and office routine.

Applications should be submitted personally to :—

The Protem Secretary,
J 7 Rediffusion Lane,
Ilesha.

LOJA ERINBURO,
Chairman

---

# WANTED

## Itagunmodi Local Council

Applications are invited for appointment as Secretary for Itagunmodi Local Council.

The successful candidate will be required to produce two bondsmen. Applications to be directed to :—

The Chairman,
Itagunmodi Local Council,
c/o X 13 Odo-Iro Street,
Ilesha.

Not later than 27th. of May 1955.
LỌYIN, ILOO.
Chairman

Printed and Published by Ijesha Press Ltd., B110 & 3149 Okesha Street, Ilesha 16 - 5 - 55